# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸLẸ

## IJỌBA OLOGO

## Ìtàn ...

**1 Awọn Ọba 3:5-15; 10:1-29**

Lẹ́hìn ìgbàtí Solomoni ti fìdí kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bi Ọba Israeli tán, Oluwa fi ara hàn án lójú àlá O sì wípé "Bèrè ohun ti emi o fi fún ọ." ẹ́ Awọn Ọba é:ú. Ọmọdekunrin ọba yìí ìbá bèrè fún owó, òkìkí, ẹmí gígùn, sùgbọ́n ko bèrè awọn nkan wọ̀nyi, dípò awọn nkan wọ̀nyi, o bèrè fún òye lati ṣe ìdajọ àwọn ènìyàn Ọlọrun. NI idahun si ìbéèrè rere yìí, Oluwa fun Solomoni ni ọkan ọgbọ́n ati ìmòye - tobẹ̀ẹ́ tí kò ti isi ẹnikan ti o dabi rẹ̀. Boríborí gbogbo rẹ Ọlọrun tún bùkún fun un, O si tún ni òkìkí, ọrọ̀ ati ẹ̀mí gígùn.



Ni àkókò ijọba Solomoni, awọn ara Israeli ngbádùn, wọn si tún ni alaafia débi wípé wọn tún nṣe aṣeyọri ni gbogbo ọ̀nà wọn. Awọn irin ÓmetalÒ tó ṣe iyebiye di ọ̀pọ̀ ni Jerusalemu ni akoko rẹ̀, fàdákà ÓsilgberÒ si dabi okuta pípọ̀ Óẹ́ Awọn Ọba ẹ̀ò:ẹ̀íÒ. Ní àfikún tẹmpili ti Solomoni fi okuta iyebiye pẹlu wúrà kọ́ fun Oluwa, o tún kọ́ ààfin pẹlu gbọ̀gàn idajọ́ fun ara rẹ̀, o tún kọ ile fún àwọn ẹsin ati àwọn ẹlẹsin rẹ̀. Awọn ọlọ́lá, oloye ati awọn ọba wá lati gbogbo ayé lati wa kí Solomoni ki wọn si tún ta á lọrẹ. Gbogbo ayé si nwá ojú Solomoni, lati gbọ ọgbọ́n rẹ̀, ti Ọlọrun ti fi si i li ọkan Óẹ́ Awọn Ọba ẹ̀ò:ẹ̀èÒ.

Lára àwọn ènìyàn nlánlá tí o wá bẹ Solomoni wò, ni a ti rí ayaba ti o ni ọrọ̀ ti o si jẹ́ arẹwà, ẹniti ó wá lati Ṣeba. O fẹ́ lati wo ohun ti àwọn ènìyàn nsọ nípa ọba Israeli bo ba ríbẹ̀ẹ̀. Ayaba Ṣeba dán Solomoni wò pẹlu awọn ìbéèrè tó le, bẹẹ nâa ni Solomoni fi èsì tó yanilẹnu dáhùn. Bi o ti ṣe wípé, ibi gbogbo tí ayaba Seba ba wò, o njẹ iyalẹnu fun un, sùgbọ́n bi Israeli ṣe ri pẹlu gbogbo ogo rẹ, ko jasi nkankan, bí a ba fi we ijọba ologo ti Ọlọrun ti pèsè sílẹ̀ fun ọ.

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọ̀ọkan tán.

**1.** Kini Jesu se ileri fun awọn ènìyàn Rẹ̀?

**Johannu 14:2**
Nínú ilé Baba mi ọ̀pọ̀lọpọ̀ _______ li o wà: ìbá mase bẹ́ẹ̀, emi iba ti sọ fun nyin. Nitori emi nlọ ìpèsè _______ silẹ fun nyin.

**2.** Kini a mọ̀ nipa ibi ti Jesu npèsè yìí?

**Isaiah 65:17**
Sa wò ó, emi o dá ọrun _______ ati ayé titun; a kì yíò ránti awọn ti isaaju, bẹeni nwọn ki yíò wa si àyà.

**Heberu 11:16**
Sùgbọ́n nisinsinyi nwọn nfẹ́ ìlú kan tí o dára ju bẹẹ lọ, eyini ni ti ọrun: nitori náà oju wọn ko ti Ọlọrun, pe ki a maa pe oun ni Ọlọrun wọn; nitori ti o ti pèsè _______ kan sílẹ̀ fun wọn.

**Matteu 5:5**
Alábùkún-fun li awọn ọlọkan tútù: nitori nwọn o jogún _______.

**Isaiah 65:21**
Nwọn o sì kọ _______, nwọn o si gbé inú wọn; nwọn o si gbin ọgbà àjàra, nwọn o si jẹ eso wọn.

Àkíyèsí: Ọ̀rọ̀ ìyàlẹnu! Ọlọrun ti pèsè ọrun titun, ayé titun ati ìlú titun fun awọn ènìyàn Rẹ̀. Awọn olododo yíò jogún ibùgbé ologo èyí tí Jesu kọ́. (Johannu 14:2), pẹlu orilẹ-èdè ìyanu ni ìgbà ayé titun ti awọn ènìyàn yio kọ funrara wọn (Isaiah 65:21).

**3.** Kini ohun tí o tun kù tí a mọ̀ nipa ìlú mímọ́ náà?

**Ifihan 21:16**
Ilu náà si lelẹ ni ___________ li ọgbọgbà, gígùn rẹ ati ìbú rẹ sì dọ́gba: o si fi ifefe ni wọn ìlú náà, o jẹ _______ _______ furlọngi: gígun rẹ ati ibu rẹ ati giga rẹ sì dọgba.

**Ifihan 21:2**
Mo si ri ìlú mímọ́ nì, Jerusalemu titun nti ọrun sọkalẹ̀ lati ọdọ __________ wá, ti a mura sílẹ̀ bi ìyàwó ti a ṣe lọṣọ fun ọkọ rẹ̀.

**Ifihan 21:10,12**
O si mu mi lọ ninu ẹ̀mí si òkè nlá kan tí o ga, o si fi ìlú nì han mi, Jerusalemu mímọ́ti nti ọrun sọkalẹ̀ lati ọdọ Ọlọrun wá, O si ni odi nla ati gíga, o si ni ẹnubode __________, ati ni awọn ẹnubode náà angẹli mejila, ati orukọ ti a kọ sara wọn ti ise orukọ awọn ẹ̀yà mejila ti awọn ọmọ Israeli.

**Ifihan 21:18**
Ohun ti a si fi mọ _______ náà ni __________; ilu náà sì jẹ́ kiki wura, o dàbí dígí ti o mọ́ kedere.

**Ifihan 21:21**
Ẹnubode mejejila jẹ perli mejila; olukuluku ẹnubode jẹ perli kan; ọ̀nà igboro ìlú náà sì jẹ́ kiki ___________, o dabi digi dídán.

Àkíyèsí: Ìlú mímọ́ náà jẹ́ onibú mẹrin (square), gigun rẹ tó ìwọ̀n ẹgbẹ̀rún mejila furlongi (12,000) (furlongi kan je ida kan ninu ida mejọ ibusọ) tabi ẹgbẹrun kan aabọ (1,500) ibùsọ̀. Yíò sọkalẹ lati ọrun si ayé titun nibiti orí òkè Olifi wa bayìí (Sekariah 14:4). Ẹyọ kọ̀ọkan ẹnubode náà jẹ́ perli kọ̀ọkan (Ifihan 21:21), ati ìwọ̀n odi Jasperi rẹ jẹ́ ogoje igbọnwọ le mẹrin (144 cubits) (Ifihan 21:17), tabi igba o le mẹrindinlogun ẹsẹ (216 feets) ni gigun (ẹsẹ kan jẹ́ inṣi mejidinlogun) (18 inches).



**4.** Kini Bibeli sọ nípa ìpèsè ounjẹ ati omi ni ìlú náà?

**Ifihan 22:1**
O si fi _________ omi ìyè kan han mi, ti o mọ́ bi kristali, ti nti ibi ìtẹ́ Ọlọrun ati ti Ọdọ-Aguntan jade wá.

**Ifihan 22:2**
Li ààrín igboro rẹ, ati níhà ikinni keji odo náà, ni igi _______ gbé wa, ti ima so oniruuru eso mejila, a si máa so eso rẹ li ososu; ewé igi náà si wa fun mímu awọn orilẹ-èdè laradá.

Àkíyèsí: Odò omi mímọ́ tí kò le gbẹ n tú jade lati ibi ìtẹ́ Ọlọrun jade, ati igi ìyè n so eso rẹ ni ososu. Igi iyanu yìí ati ewé rẹ n pèsè ìwòsàn ikú ati ìyè àìnípẹkun. Ni afikún, awọn ènìyàn mímọ́ Ọlọrun yíò ma ri ounjẹ wọn ni ile wọn ni orilẹ-èdè wọn (Isaiah 65:21). Ounjẹ awọn ènìyàn Ọlọrun yíò jẹ èyí tí wọn ma n jẹ tẹ́lẹ̀ kí ẹṣẹ to wọ ayé - eṣo, ohun ọgbin ati aláwẹ̀ (Genesisi 1:29,31). Adùn wọn yíò dùn lọ́pọ̀ ti èròjà asara loore wọn yíò sì pé.

**5.** Bawo ni gbígbé ni ọrun yíò ṣe yàtọ̀ si gbígbé ni ayé?

**A. Isaiah 35:5**
Nígbà náà li ojú awọn ___________ yíò là.

**B. Isaiah 35:5**
Etí awọn ___________ yíò sì sí.

**D. Isaiah 35:6**
Nígbà náà li awọn arọ yíò _________ bi agbọrin, ati ahọn odi yíò kọrin, nítorí omi yio tú jade li aginjù, ati ìsàn omi ni ijù.

**E. Isaiah 65:25**
Ikooko ati ọdọ-agutan yíò jumọ jẹ pọ̀, kiniun yíò sì jẹ koriko bi akọ-malu: erupẹ ni yíò jẹ ounjẹ ejò. Nwọn ki yio __________, tàbí kí nwọn panirun ni gbogbo òkè mímọ́ mi, li OLUWA wí.

**Ẹ. Isaiah 11:6**
Ikooko pẹlú yíò ma ba ọdọ-àgùtàn gbe pọ̀, ___________ yíò si ___________ pẹlu ọmọ ewurẹ; ati ọmọ malu ati ọmọ kiniun ati ẹgbọrọ ẹran abọpa yíò ma gbé pọ̀; ọmọ kékerè yíò sì ma dà wọ́n.

**F. Isaiah 35:1**
Aginjù ati ilẹ gbígbẹ yio yọ̀ fun wọn; ijù yio yọ̀, yio si __________ bi lili.

**G. Isaiah 33:24**
Ati awọn ara ibẹ̀ kí yio wípé, ___________ mi kò yá: a o dárí aisedeede awọn eniyan ti ngbé ibẹ jì wọn.

**GB. Ifihan 21:4**
Ọlọrun yíò sì nu om gbogbo nù kúrò li ojú wọn; ki yíò sì sí ___________ mọ́, tàbí ọ̀fọ̀, tabi ẹkun, bẹeni ki yio si irora mọ́: nitori pé ohun atijọ ti kọja lọ.

**6.** Irú ara wo ni awọn ayanfẹ yíò ni?

**Filippi 3:20,21**
Nitori ilú-ibilẹ wa mbẹ li ọrun: lati ibiti awa pẹlu gbé nfojusọna fun Olugbala, Jesu Kristi Oluwa: Ẹniti yio sọ ara ìrẹ̀lẹ̀ wa di ọtun kí o le ba ara __________ rẹ mu, gẹ́gẹ́ bi ise agbara nipasẹ eyiti oun le fi tẹ ori ohun gbogbo ba fú ara rẹ̀.

**7.** Njẹ ara Jesu dájú tabi iwin ni Oun?

**Luku 24:39**
Ẹ wo ọwọ́ mi ati ẹsẹ̀ mi, pé emi tikarami ni: ẹ di mi mú kí ẹ wo o; nitori ti _________ kò li ______________ oun ___________ lara, bi ẹnyin ti ri ti mo ni.



YOR-SP8.indd 1

12/6/12 11:48 AM

Àkíyèsí: Ara Jesu lẹhin ti o jinde dájú, o ni ẹran ara ati egungun ti a le fi ọwọ kan lati mọ. Awọn ọmọ ẹhin kọ́kọ́ rò wípé iwin ni, nígbà tó dédé yọ siwọn lojiji, sùgbọ́n lẹhin ìgbàtí wọn ti fi ọwọ́ kan An tí wọn si ri wipe O si jẹun (Luku 24:40-43), wọn mọ̀ pe O dájú pe oun ni. Lẹhin ogoji ọjọ, Jesu mú wọn jade lọ tìtí de Betani, O si gòkè lọ sí ọrun (Luku 24:50,51). Awọn angẹli ti o yọ si awọn ọmọ ẹhin ṣọ fun wọn pé "Jesu náà yi, (tí o ni ẹran ara ati egungun)...yio pada bẹ̀ẹ̀ gẹ́gẹ́ bi ẹ ti ri i ti o nlọ sí ọrun." Ise Awọn Aposteli 1:11. Lati ìgbà ifarahan Rẹ̀, Jesu ti ni aṣọpọ̀ pẹlu iran ènìyàn, bẹ̀ẹ̀ pẹlu ni o si tun jẹ́ ẹni ọrun títí lai.

**8.** Ileri to n gbani niyanju wo ni a tun rí?

**Ise Awọn Aposteli 3:20,21**

Ati ki o ba le ran Kristi, tí a ti yàn fun nyin, ani Jesu, Ẹniti ọrun kò le saima gbà títí di ìgbà ___________ ohun gbogbo, ti Ọlọrun ti ṣọ lati ẹnu awọn Woli rẹ mímọ́ ti nwọn ti mbẹ nigbati ayé ti ṣẹ̀.

Àkíyèsí: Ogo ni fun Ọlọrun, ohun rere gbogbo ti o ti sọnu lati ìgbàtí ẹ̀ṣẹ̀ ti wọ ayé ni a o dá padà ninu ijọba titun ti Ọlọrun. Gbogbo ènìyàn ni yio ma a fẹran ara wọn, gba ara wọn gbọ́ debi wipe wọn yio si tun ma a ran ara wọn lọ́wọ́ tọkantọkan. Pẹlu abajade yii, kò ni sí ìwà ipá mọ́ (Isaiah 60:18), kí yíò sì tún sí oníkúpani, abanijẹ, alaisootọ, aṣọ̀rọ̀-ẹni-lẹhin, àábò-tí-kò-dájú, ìrẹ̀wẹ̀sì, ewu, ìjákulẹ̀, ibanujẹ-ọkàn mọ́. Sùgbọ́n yio jẹ ajọyọ̀, ìdùnú, ìtẹ́lọrun, ìgbé-ayé ọ̀pọ̀ ní ayérayé.

**9.** Se ìkorò ati ọgbẹ́ ọkàn lati inu iriri ayé yio tún damu awọn ènìyàn ni ọrun?

**Isaiah 65:17**

Sa wò ó, emi o da ọrun titun ati ayé titun; a kì yíò ___________ rántí awọn ti isaju, bẹẹni nwọn kì yio wa si àyà.

Àkíyèsí: Ọ̀rọ̀ náà "to wa sí ọkàn" o rọrun lati tumọ "to wà nínú ọkan". Oluwa n sọ̀rọ̀ ninu ẹṣẹ yi pé ikorò ayé kò ni mu ibanujẹ wa fun awọn ayanfẹ́ Rẹ̀ ni ọrun.

**10.** Njẹ awọn ènìyàn yio da ara wọn mọ̀ ni ijọba Ọlọrun titun?

**1 Korinti 13:12**

Nitori pe nisinsinyi awa nriran baibai ninu awojiji; sùgbọ́n nígbà náà li ojúkojú: nisinsinyi mo mọ̀ li apakan; sùgbọ́n nígbà náà li emi o _________ gẹ́gẹ́ bi mo si ti di mímọ̀ pẹ̀lú.

Àkíyèsí: Dájúdájú a o da ara wa mọ̀ nipa ìrí ojú, ìrìn, iṣesí, ìsọ̀rọ̀ wa, ati bẹ̀ẹ̀bẹ̀ẹ̀ lọ. Oore ọ̀fẹ́ lati mọ ara wa ni ọrun yio pọ̀ si. Ọrun yio jẹ ẹbi alayọ tí a kò le e tùká.

**11.** Kinni ìlérí aláyọ̀ tó tún kù ti Ọlọrun tún ṣèlérí fun wa nía ìjọba Rẹ̀ to nbọ?

**A. Isaiah 35:10**

Awọn ẹni-iràpadà OLUWA yio pada, nwọn o wa si Sioni ti awọn ti orin, ___________ ainipẹkun yio sì wa li ori wọn: nwọn o ri ayọ ati inú didùn gbà, ikaanu oun imi-ẹdun yio sì fò lọ.

**B. Orin Dafidi 16:11**

Iwọ o fi ipa ọ̀nà ìyè hàn mí; ni iwajú rẹ li ẹkún ayọ wa: li ọwọ ọtun rẹ ni ___________ láíláí.

**D. Sekariah 8:5**

Ìgboro ilú yio sì kún fún ọmọdekunrin, ati ọmọdebinrin, ti n ___________ ni ita wọn.



**E. Isaiah 40:31**

Sùgbọ́n awọn ti o ba dúró de OLUWA, yio tun agbara wọn ṣe; nwọn o fi ______ gun òkè bi idì, nwọn o sare, kì yio si _________ wọn; nwọn o rìn, ___________ kì yio sì mu wọn.

Àkíyèsí: Awọn àyànfẹ̀ yio ma fò bi awọn angẹli ni ìwọ̀n tó kọja ti iná. Nígbàtí wọn yio jogún ohun gbogbo (Ifihan 21:7), wọn tún le ṣe àbẹ̀wò sí ayé miran ni àárín iṣẹju kan. Gẹ́gẹ́ bi ìwé mímọ́, Ọlọrun da aye miran tí kò subú (Jobu 1:6; Heberu 1:2, 11:3).

**12.** Njẹ a le fi ọ̀rọ̀ ẹnu ṣe apejuwe ijọba Ọlọrun titun?

**1 Korinti 2:9**

Sùgbọ́n gẹ́gẹ́ bi a ti kọ ọ pé, Ohun tí ojú kò ri, ati ti etí kò gbọ, tí kò sì wọ ___________ ___________ lọ, ohun wọnni tí Ọlọrun ti pèsè sílẹ̀ fun awọn ti o fẹ ẹ.

Àkíyèsí: Emi ati ìwọ ni ipò ti a wà bayi, a kò le e ronú ohun ìyanu ti Ọlọrun ti pèsè sílẹ̀ fun awọn ọmọ Rẹ. Kò si ọ̀rọ̀, èrò tàbí àlá ti o le fi iran alayọ ọrun alailabùkù hàn. Bi o ti lẹ wu ki a ri ipọnjú to ni ayè yìí, ti a ba ti le de ọrun, èyí ju idanwo ayé lọ. (Romu 8:18).

**13.** Kinni èrè to pọjù ni ijọba Ọlọrun titun?

**Ifihan 21:3**

Mo si gbọ́ ohun nla kan lati orí ìtẹ́ nì wá, nwipe, kiyesi i, àgọ́ Ọlọrun wà pẹlu awọn ènìyàn, oun o sì maa ba wọn gbé, nwọn o si maa jẹ ènìyàn rẹ, ati Ọlọrun tikararẹ yio wà ___________ wọn, yio sì maa jẹ Ọlọrun wọn.

Àkíyèsí: Gbà á gbọ́, kí o si dúró pẹlu iyanu! Ọlọrun yio gbé pẹlu awọn eniyan Rẹ̀ ni ayé titun dájúdájú. Kò sí ohun ti a le fi we ogo ati ayọ lẹ̀kúnrẹrẹ yìí.

**14.** Kilo le mu ki awọn eniyan kan ma yẹ fun ijọba Ọlọrun?

**Ifihan 21:27**

Ohun alaimọ kan ki yio sì wọ inu rẹ rara, tàbí ohun ti nsiṣẹ___________ ati èké; bikose awọn ti akọ sinu ìwé ìyè Ọdọ-Agutan.

**Ifihan 21:7**

Ẹniti o ba ___________ ni io jogun nkan wọnyi; emi o si maa jẹ Ọlọrun rẹ, oun o si maa jẹ ọmọ mi.

Àkíyèsí: Ẹ̀ṣẹ̀ a ma n ba eniyan jẹ́, nitori náà a ko ni gba ẹ̀ṣẹ̀ láàyè ni ọrun, bikoṣe bẹẹ ọ̀tẹ̀ yio tun padà bẹ̀rẹ̀. (Wo akori afikún "Ijọba Ọlọrun".)

**15.** Kini mo le ṣe pẹlu ẹ̀ṣẹ̀?

**1 Johannu 1:9**

Bi awa ba jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wa, olootọ ati olododo li oun lati dari ẹ̀ṣẹ̀ wa jì wá, ati lati __________ wa nù __________ ninu aiṣododo gbogbo.

Àkíyèsí: Bi mo ba tọrọ idariji ẹ̀ṣẹ̀ lọ́wọ́ Jesu, Yio dariji mi, yio si tun wẹ mi mọ́ kúrò ninu ẹ̀ṣẹ̀, A tun ṣọ mi dọmọ Rẹ̀.

**16.** Kini Jesu pè ni ìlànà aṣeyọri ninu ayé yìí ati èyí to nbọ?

**Matteu 6:33**

Sùgbọ́n ẹ tètè maa wá __________ ___________ na, ati odo rẹ; gbogbo nkan wọnyi li a o si fi kun un fun nyin.

Àkíyèsí: Èyí jẹ́ ohun ti Ọba Solomoni ṣe nigbati Ọlọrun bèrè, "Kini o fẹ́?" Èrò ti o kọ́kọ́ rò ni ijọba Ọlọrun ati ododo rẹ. Lẹhin náà, èrè ijọba ologo tẹle. Èyí pẹlu yio sẹlẹ nigbati awa náà ba nkọ́kọ́ wa ijọba Ọlọrun.



# Èsì Rẹ

Mọ èyí dájú wípé Ọlọrun ni o nṣe àkoso gbogbo ayé, njẹ́ iwọ náà fẹ́ ki Ọlọrun gba gbogbo àkoso ayé rẹ bí?

ÌDÁHÙN: ______________

# Àfikún

Ipele yìí yio fun wa ni awọn ọ̀rọ̀ afikun lati tun mu wa kẹkọ tẹ̀síwájú.

## Ijọba Ọlọrun

Bibeli jẹ́ akọsílẹ̀ ìjọba meji tí wọn kò sọ̀kan nígbàgbogbo - ìjọba Ọlọrun ati ìjọba Èṣù. Ohun tí iwaasu Jesu dá le lori ni Ìjọba Ọlọrun. A darukọ ìjọba Ọlọrun ju ọgọrun ìgbà lọ ninu Majẹmu Titun nìkan, ọ̀pọ̀ ninu wọn wà ninu òwe Jesu. Ninu ẹkọ́ Rẹ̀ ni a ti mọ wipe Ìjọba Ọlọrun pin si ọ̀nà meji - ẹ̀mí ati òtítọ́.

Awọn ọmọ ìjọba ọrun ti ẹ̀mí, ni Ọlọrun njọba t'Ó sì nṣe akoso ọkan wọn. Ki a to di ẹni ìràpadà, ìtẹ́ ọkan wa jẹ́ ti Satani, ẹ̀ṣẹ̀ ati ara. Sùgbọ́n lẹhin ti a ti ri idariji gbà ati agbara Jesu, ni ìdè náà já. Idi niyi ti Paulu fi sọ pé, "Nitori naa ẹ máse jẹ ki ẹ̀ṣẹ̀ ki o jọba ninu ara kíkú nyin, ti ẹ o fi maa gbọ́ ti ifẹkufẹ rẹ̀. ... Nitori ẹ̀ṣẹ̀ kì yio ni ipa lori nyin: nitori ẹnyin kò si labẹ ofin, bi ko ṣe labẹ oore-ọfẹ." Romu 6:12,14. "Sùgbọ́n bi o ba ṣepe ìka Ọlọrun li emi fi nle awọn ẹmi èṣù jade, kò si aniani, Ìjọba Ọlọrun de ba nyin." Luku 11:20.

Lẹṣẹkẹṣẹ ti ẹnikan ba ti gba Kristi, o di ọmọ Ijọba Ọlọrun ti ẹ̀mí. Nitori idi èyí ni Jesu ati Johannu onitẹbọmi fi bẹ̀rẹ̀ iṣẹ iranṣẹ wọn lati ma a bẹ awọn ènìyàn lati ronúpìwàdà, "nitori ijọba ọrun kù sí dẹ̀dẹ̀." Matteu 3:2; 4:17. "kù si dẹ̀dẹ̀" tumọ si wípé o wa ni ìkáwọ́ tabi ohun ti a le ri ni ìtòsí lọ́wọ́ lọ́wọ́. Nitori ìdí èyí ni Jesu fi wípé, "Ìjọba Ọlọrun ki iwá pẹlu àmì:Bẹ̀ẹ̀ni nwọn kì yio wipe, Kiyesi i nihin tabi kiyesi i lọhun! sa wo o, ijọba Ọlọrun mbẹ ninu nyin." Luku 17:20,21. Ní kété ti ẹnikan ba ti ṣe iribọmi tan, o kúrò ninu ijọba okunkun ti Satani, o si darapọ mọ́ Ijọba imọlẹ̀ ti Ọlọrun.

Gbogbo awọn ọmọ lẹhin Kristi tootọ jẹ́ aṣoju fun gbogbo ayé lati inu ijọba ẹ̀mí Ọlọrun. Aṣoju lati orilẹ-èdè miran ma nṣọ èdè to yàtọ̀, wọ aṣọ to yàtọ̀, jẹ ounjẹ to yàtọ̀, ma nná owó to yàtọ̀ ati pẹlu yio ni àṣà to yàtọ̀. Ni ọ̀nà kanna, bi i aṣoju Kristiani, a gbọdọ̀ kiyesi daadaa lati ṣoju ijọba Oluwa wa nipa ọ̀nà ti a ngba jẹun, sọ́rọ́, wọṣọ, pẹlu bi a ṣe nlo àkókò ati owó wa.

Ni ọjọ́ kan awọn ènìyàn Ọlọrun yio jogun otitọ, eyi ni ni ijọba Ọlọrun ti a ṣọ̀rọ̀ rẹ ninu ẹkọ yii ni ojúkojú. Ijọba yii ni a n bèrè fun nigbati a ba n gbadura Oluwa, "Ki ijọba rẹ dé." Matteu 6:10. Ijọba ti ẹ̀mí Ọlọrun yio di gbigbe kalẹ pátápátá lẹhin ijọba ẹgbẹrun ọdun, idajọ ati ija ti a juwe ninu Ifihan ori ogún (20).

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP8.indd 2 12/6/12 11:48 AM